**Akiyesi**

A nfẹ Ẹniti yio ma a wa ta Iwe Irohin Imọlẹ. Ni agbegbe Ilorin tabi Ilu miran. E kowe si odo Ọgbeni R. O. Adedeji Esq. Ni P. O. Box 12 Ilorin

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ „DE" OKUNKUN PARADA.

**Notice**

HELLO! HELLO!!

For all your Electrical appliances & work Consult:- Sijuwade Elect. Stores.

Stockist of Elect. Cables, Fittings an accessories. Workshop & Showroom 15 Jebba St. (East) Ebute Metta.

VOL. III No. 149 MONDAY MAY 23 — MAY 29 1960 KỌBỌ KAN (1d)

# Akintola soro die nipa irin ajo re s'ilu Oyinbo

OLOYE S. L. AKINTỌLA TI IṢE OLOTU IPINLẸ IWỌ ORUN NAIJIRIA SỌ FUN AWỌN ONIWE IROHIN NIGBATI O DẸHINDE LATI IRIN AJO RẸ SI ILU OYINBO, NIBITI NWỌN GBE TI LỌ ṢE IGBIMỌ NIPA OMINIRA ILẸ NAIJIRIA SỌ WIPE "ON KO RI SI IRU IPADE IGBIMỌ TI NWỌN LỌ ṢE YI, KO SI OHUN AJEJI KAN, TABI OHUN TI O FI YATỌ SI OHUN AJEJI KAN, TABI OHUN TI O FI YATỌ SI OHUN KANNA TI WỌN TI MU ẸNU KAN NI ODUN 1958, HOWU! A HA LE TI ỌNA TIUN-TIUN YẸN WA SILU OYINBO MA WA PALỌ.



Awọn enia pataki ti o nbẹ nibi ti Oloye Akintọla gbe ti sọrọ yi ni Oloye J.A.O. Ọdẹbiyi, ti iṣe Olori Alabojuto owo Ijọba, Iwọ Orun.

Ọgbẹni S. O. Ighodaro Agbẹjọro Ijọba, ati F. R. A. Williams Amofin ati Onimọran Ijọba.

Igbimọ ti a lọ ṣe ko le pari ọrọ ti a balọ silu Oyinbo na Ọgbẹni Sir James Robertson ni wọn tun ni lati yan wipe ki o lọ pari ọrọ yi ninu Igbimọ nla kan ti ao tun ṣe ni ilẹ Naijiria.

Ijọba Gẹẹsi ti pari eto Ominira na silẹ, ṣugbọn awọn Ipinlẹ Naijiria ni ọrọ ku si lọwọ.

Ohun kan lo yatọ ninu ofin eto Ominira na, eyi ni wipe, ẹnikẹni ti a ba fẹ yan lati j'oye Gomina Agba, oluwarẹ ni lati jẹ ẹniti Olotu Ijọba Alapapọ-ṣe fi aṣẹ si.

Ẹwẹ ki Olotu Ijọba Alapapọṣe to jẹ ọhẹn si yan ẹnibẹ, Olotu na ni lati wọle Igbimọ papọ pẹlu anwọn Olotu yoku.

Bakanna ni a o ṣe nigbati a ba fẹ yan Adajọ Agba ati nigbati a ba fẹ yan Oluwadi tabi Aṣoju nilẹ Naijiria Igbimọ yi tun fi ohun ṣọkan wipe ko ni si ibudogun ajeji kan ni ilẹ Naijiria, ati bi ede ko yede kan ba bẹ silẹ larin Gẹsi ati Naijiria, o ni lati jẹ ohun ti igbimọ Nla (House of Representative) lọwọ ninu rẹ, ninu awọn nkan ti ipinlẹ iwọ orun fẹ ni, ki ijọba Gẹsi kọ awọn ọmọ wa ni iṣẹ ogun, ki nwọn si fun wa ni orisirisi nkan ija ogun, lẹhin Ominira ki rẹpọ si wa larin Ijọba Gẹsi ati Ijọba Apapọṣe, ki nwọn si kọ wa ni iṣẹ ẹro.

## Ohun ti o da ijongbon sile ni ile ise Reluwe

DR. TESILIMI O. ELIAS Sọ wipe on ati awọn isọngbe on damu nigbati awọn gbọ wipe awọn Oṣiṣẹ Reluwe ko ni wa sibi iwadi na. Ijọba fẹ ki nwọn te-te pari ọrọ iwadi yi larin ọjọ meje. Ọgbẹni Ogunsanya dahun wipe ifẹ inu Ijọba ni wipe ki a se iranlọwọ fun awọn ọlẹjọ rẹ, iyẹn ni aṣiwaju awọn oṣiṣẹ ti nwọn gbe ju si ẹwọn fun ẹsun dida ruke-rudo silẹ.

Dọkita Elias sọ wipe, inu awọn yio dun gidigidi bi awọn oṣiṣẹ ọgba Reluwe ba le bọ siwaju wa ro ti ẹnu wọn, nipa ohun ti Olotu wọn fi ṣe wọn nitorina ko nṣe ẹtọ wa ki a gbọ apakan ẹjọ na, ki a ma si gbọ ti apa keji ki a si bẹrẹ ẹjọ ni dida.

Nitorina bayi ni mo fẹ ki a ṣe eto ẹjọ na, awọn oṣiṣẹ ọgba Reluwe ni Olufi ẹjọ sun ninu ọrọ yi, awọn ni mo fẹ ki o o kọkọ ro ẹjọ fun ọjọ mẹrin, awọn olotu ọgba Reluwe yio fesi dahun si ẹjọ, wọn ti nwọn fi sun fun ọjọ mẹrin, awọn ti ko nṣe oṣiṣẹ tabi olotu, aye ọjọ meji wa fun wọn lati rojọ, Ọjọ meji si tun wa fun awọn oṣiṣẹ lati dahun si ọrọ ti Olotu ba fi purọ mọ nwọn. Aye ọjọ meji si tun wa fun awọn olotu lati fesi si ọrọ irọ ti awọn oṣiṣẹ pa mọ wọn. Ọjọ meji wa fun awọn oluwadi lati ṣe ayẹwo ẹri ti nwọn jẹ yeke-yeke.

Bi ẹjọ na ba tun ti nlọ si, ẹ o ma gbọ nipa rẹ.

## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLỌWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ




MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pataki ta ṣe ni Aṣepe fun Awọn ọmọde, ati nlo ogun yi fun ọpọlọpọ ọdun sẹhin pẹlu idanilojo fun Awọn iṣẹ ribiribi ti o ti nṣe. MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to dara pupọ fun igbona ikọ, otutu, Aiperi, Osi inu ọmọde, jẹdi jẹdi Kokoro ori ọmọde. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ki ọmọde ma nsun fọnfọn, o nmu ki ehin hihu jẹ irọ run fun awọn ọmọde, osi njẹki awọn ọmọde tobi, osi nmu wọn dan ni awọ. Ẹnyin Abiyamọ, ẹku afojuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti koṣe mani fun awọn ọmọde. Ijafara lewu pupọ, tete lọ ra ti ẹ ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo rẹ.

Igo kekere rẹ jẹ 2/6d Igo nla jẹ 4/6d

L LO RE:- Sibi kekere kan lemeta lojumo

*Wholesale Distributors*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS

6, Balogun Street West, Lagos Nigeria, Phone 22515

34, Docemo Street, Lagos, Phone 204247

# IMOLE

ESIN ORO WA-
IMOLE DE OKUNKUN
PARADA
Editorial Works & Office
16, Bmgbose Strt,
Lagos
Telephone- 21985
United Kingdom Rep.esentative
Publishing Distributing
177, Regent Street.


## Awon Oyinbo igba lai-lai Yato si ti Oyinbo isisiyi

Nigba lailai, nigbati aiye koiti lu ja ara won gegebi akoko ti isisiyi, awon oyinbo onisowo ti o mbẹ ni akoko igba na yatọ si awọn ti o wa loni yi. Bi enia ba fẹ sise, ti o si lọ si ọdọ wọn wipe, o nfẹ ki nwọn si sọbu funọ. Ohun ti nwọn kọkọ ma mu ṣe ni wipe, nwọn o fi ọrọ na si ero.

Bi nwọn ba ro ọrọ na, ti o si dogba, awọn funra wọn ni yio ranṣẹ wa pe ọ ninu ile, wipe, ki o da kian wa fi oju kan wọn nipa ọrọ rẹ. Nwọn o bere lọwọ rẹ pe, iru oja wo lo mọ ta ju.

Lẹhinti o ba ti sọ fun wọn tan, ohun ti nwọn o tun wi nipe ki o lọ wa oniduro kan wa.

Awọn Onisowo akoko na ko ni arekereke gẹgẹbi awọn ti ode oni. Kete ti o ba ti mu oniduro kan wa, ni nwọn nia ṣi Ṣọbu fun oluwarẹ. Nwọn o bere lọwọ rẹ pe" bawo ni iwọ ti ri owo si nipa ọja tita, nwọn ko fẹ mọ ohun kan nipa ibiti o gbe ti nsiṣẹ ri. Nigbogbo ọna ti awọn Onisowo nmu nkan gba nisisiyi awa enia dudu na ni afi kọ won.

Sababi eyi ni kojẹki awọn ẹlomiran ni afọri titi di oni. Bo fẹ ki enia ka iwe de ogogoro, ki o si mọ iwe de wala-lali-na, ko le ri iṣẹ ṣe, bi o ba si ni dukia lọwọ ti o si ni ẹru lọwọ ti o si ni owo lọwọ lati fi dogo, ki nwọn sa jaja gba si iṣẹ na, iwọ yio ke ṣafula fun iru wahala ti yio ri mbẹ. Nitori idi eyi, ni awọn Yoruba ṣe ma npa owe bayi wipe, Ọpa agbeleka ti ẹhin loju. Banijẹ banijẹ obi ti yio so nigba ẹrun.

## Itumo Ami Ara

Eti- Ti o ba ni ami ni eti, iwọ yio ma ri igbega ni ọna iṣẹ ti o ba tẹlẹ ni aiye, o ko si ni tarakuta ni ọjọ aiye rẹ, aṣọ (blue) tabi funfun ni o dara ki o ma lo, ohunkohun ti o ba si fẹ ṣe ni rere yala, igbeyawo, ọmọ kiko jade, iṣẹ dida silẹ tabi ile sisi ni ọjọ Aje tabi Ojọ Ọjọbi ni ki o ma fi si Ọlọrun yio fi ọmọ binrin jinki rẹ ju ọkunrin lọ.

Bere itumọ ami Ara tirẹ papa lọwọ

Onimimọ Irohin Imọlẹ

6, Ojo Road Oduabọrẹ
Mushin.

## Itumo Ala

Basiru Kẹhinde Agbado Station- sọra nitori jamba, maṣe wọkọ oju omi lasiko yi ki o ma ba ri ija yemọja.

Bere itumọ rẹ lọwọ
Joseph Alala
6, Ojo Road
Oduabọrẹ Mushin

## Owe Yoruba

Arinrin gbẹrẹ, niyio mu Oye de ile, sugbọn, a sure tete ko ri Oye jẹ.

Orisa ti on gbe Ọle kosi, Ọgbọn Ori ẹni lo ngbeniga.

Bi agbe Adiẹ gun, koni ko pa ogun ọmọ Agba toni soru ohun gbogbo lo ni.

Bi oni yio ti ri, Ọla ki ri bẹ, Ohun lo mu Babalawo d'Ifa ọrun. Ikun njẹ ẹpa Ikun nmu, ko mọ wipe ohun lo npa enia.

Ajumọbi ko kan ti anu ki alapa mu apa rẹ kole daradara. Awun gbọn, Ijapa sọ ile Aiye di awalilọ. Iwa rere l'ẹṣọ Enia.



# Bismilai Rahmoni Rahmi.

# NIPA ISLAM

Lati Qwọ:— ALFA HUSAEN MUHAMAD.
No. 10A. Thomas Street, Lagos.

## Ise Haji' (Apa-kefa)

LẸHIN TI Alihaji tiṣe umura tan ti osi ti wọ Baetil-Atiki ni yio ma wa reti ọjọ Arafa gẹgẹ bi ati ṣe wi ni ọsẹ tokọja.

Ọjọ nla si ni ọjọ yi ni ti papa. Arafa jẹ irin ibusọ (mile)mẹrinla si igboro mọka. Ni ọjọ Arafa ni wọn yio pa aṣọ dudu ti ati fi bo ile Oluwa tẹlẹ da si funfun. Awọn alihaji yio si bẹrẹ si ni lọ si ori ọdan Arafa yi lati idaji tabi oru. Enia le wọ mọto taxi tabi ki o gun ẹṣin tabi rakunmi. Ṣugbọn ju gbogbo rẹ lọ irin ẹsẹ lo-yaju fun didi ọna fun mọto nipa ọpọ ero. Arafa kiṣe oke gagara gẹgẹbi Olumọ tabi Sobi ti ale ma fi aya pọn gẹgẹbi ọpọ enia tiṣe nro. Okan jẹ ọdan g b a l a s a ni ṣugbọn ti ogbera soke diẹ yatọ si awọn aye agbegbe rẹ toku. Ni ẹgbẹ si ni oke kan wa ti anpe ni Jabali Rahamọr (Oke Anu).

Ni ori Arafa awọn Alihaji yio wa ni inu awọn agọ (tents) ti ati pa lele silẹ fun wọn ti wọn yio si ti san owo rẹ ki wọn to kuro ni M ọ k a kosi ohun ṣiṣe kan ni oke Arafa ju ọpọ adura lọ si Ọlọrun. Wọn yio si ki irun ayila ati alasari papọ ni irọlẹ. Olukuluku ninu agọ (tent) tirẹ ni ẹhin aṣiwaju ti wọn ba yan latin ara wọn. Ni ọwọ alẹ ni wọn yio wa dari si idi oke Jabali Rahamọr lati gba adura si Ọlọrun lẹhin eyi ti wọn yio dari si ibi agọ won lati m u r a idari si ile. Ni ọna ile ni wọn yio duro ni alẹ ni ilu kekere kan ti anpe ni Musidalifa. Ni eti idaji ni wọn yio tun lọ si ibi oke Muna, nibi ti wọn yio ti pa ẹran.

Ẹgbẹgbẹrun aiko mọ iye ẹran ti wọn yio pa ni agbo, aguntan, ewurẹ, rakunmi ati malu ni iwọn bi Olukuluku ba ti ni agbara mọ. Wọn ko ni gbe ọkankan lọ ni ibẹ bi ko ṣe pe wọn yio fi wọn silẹ fun awọn a l a i n i lati gbe wọn lọ. Ọjọ mẹta ni awọn Alihaji yio gba ni Muna. WO IYOKU NI OJU EWE KERIN

---


## FOR SALE

### Second Handed Cutting Machine (GUILLOTINE)AT Moderate Price

Consult:-
Manager Modupe Printing Press
16, Bamgbose Street, Lagos. Phone 21985


---

# Kini a npe ni Islam.?

Lati Qwọ:— MAULVI N. SAIF. Lagos.

Islam jẹ ede Larubawa, itumọ rẹ ni eniti o gba latima sin Ọlọrun. awa ti a npe ni Musulumi gbagbọ wipe Ọlọrun ọba to to sin. Gbogbo ẹsin aiye yi lo si gbagbọ bẹ pe Ọlọrun lo to sin Iyẹ ni wipe ki agba fun Ọlọrun. Eyi lo jẹki a ma pe awọn ẹsin ti o gba lati ma sin Ọlọrun ni ẹsin Islam. Ẹsin Islamti wa ọjọ pẹ, ṣugbọn nigati Anọbi ti ao fi ẹsin Islam ran koiti de ni torina Ọlọrun fun ra rẹ ko ba wọn pe ẹsin yi ni Islam.

Odabi ọmọ ti a bi, ti a koiti fun ni suna. A fun ni orukọ, a ko fun ni orukọ, iyẹn ko wipe ki ọmọ na ma wa.

Ife dara, o si rẹwa pupọ, a si gbagbọ pe, Ọlọrun lo nje Ifẹ. bẹ na ni a gbagbọ pe ẹnikẹni ko le ni ifẹ ayafi ki oluwa rẹ gba ofin Ọlọrun. Ọmọ ti ko ba gba ofin Baba rẹ ibọ. Baba na ko ni fẹran rẹ.

Nitorina ki a le da ifẹ si arin Ọlọrun ati e n i a, Ọlọrun fẹ ki a kọkọ pa ofin rẹ mọ fun ara wa.

Anọbi kan ni Ọlọrun fi awọn Ofin rẹ ran. Anọbi M u s a mu ofin diẹ wa, nwọn jẹ mẹwa. Jesu si kọ awọn enia pe ki nwọn gba ofin na gbọ. ṣugbọn Anọbi Muhamad tun mu ofin diẹ wa si, nwọn si wa ninu iwe mimọ Alukurani. Bi a ba pa awọn ofin nwọnyi, Ọlọrun yio fẹran wa, yio si jẹki a niiari ninu aiye yi, dajudaju a o si jere Alijanoa.



MAULVI N. SAIFI

WO OJU EWE KERIN

---


## Iwe Ilana Ifa, Yanrin tite, Etutu Sise, Iwosan ati Egbogi Ajebidan.

Ti o ba ni Iwe yi lọwọ- Oṣo Aiye, Ajẹ Enia - majeki Tẹnisunwọn, Alapeta ati awọn ibaba ati ikoko ko na lagbara lori rẹ Ohunkohun ti o ba dawọle rere ni yo ma jasi Babanla Awure ati Ogun Ajẹbidan wa nibẹ pẹlu tete ra tirẹ ki o to tan, awọn Babalawopapa wa ndura lọdọ wa ni. Iye Owo 10/6d.

2. Itumọ Ala ati Ayẹwo Odu Ifa 2/6d.
3. Agbara Igba Iwaṣẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan 3/-
4. Gbedegbeyọ Hausa 2/6 5. Itumọ Ami Ara 3/-
6. Ewọ Yoruba ati Etutu 3- 7. Ma fọmọ y ọ m o Arofọ 1/6d Turari Itaja Adura Tetedamilohun, ati Iṣẹgun Aiẹ pẹlu Psalmu Ajẹbidan 15/6.

Fi Owo ranṣẹ si Ọgbẹni J.O. Shoyinka 6, Ojo Road (Oduabọre Mushin.


---


## AKIYESI PATAKI

### Antoin Tabs! Antoin Tablets!! Antoin Tablets!!!

KABIYESI,! KABIYESI ỌBAKOSO MO FẸNUN ṢỌ ỌWỌ

Ẹyin ọmọ ara aiye mo ba yin yọ lọkunrin, lobirin, lagba ati lọmọde Ẹ ku a fo juba Egbogi pataki ti a ṣe Iwadirẹ fun:- Akọ Igbona, Ara riro, LukuLuku ati Iba pọnju, (Yellow Fever) pẹlu Itọ pupọn lati ọwọ awọn Dọkita wa ni Ilu Oyinbo.

(Reduces Fever, Relieve Pains)
For Children and Adults.
O daju Hawun Irohin ko to afojuba,
Bere lọwọ Onisegun Adugbo rẹ, tabi Lọwọ Ọgbẹni wa.

Hassan Commercial Medicine Stores
18A Bishop Street, Lagos. Phone 23745


---

Advertisement No. 62

# IMPORTANT NOTICE

## Payment of Income Tax by Cheque.

It is notified for general information that as from the date of this notice all Cheques issued for payment of Income Tax which are drawn on a branch of a bank situated in a Town other than the one in which the Federal Inland Revenue Department's Office is situated must be endorsed "Commission to Drawer's Account" and the full signature of the Drawer must appear against this endorsement.

2. Attention is drawn to the facility provided by the Post Office which will issue Money Orders free of the usual charges for amounts up to the tax payable, on production of the Assessment Notice or Payment Note.

FEDERAL BOARD OF INLAND REVENUE.

## Amerika tun gbe Omiran de o!

Irohin de etigbo wa wipe awon ara Amerika tun ti nmura lati ran ero miran lo si inu Osupa ni Oke-Orun a gbo wipe bi nwon ba se ero titun na tan, yio wiwo ni nkan bi Odunrun esun (300lbs) won tun so wipe ki ise wipe o ma lo funrare lati isale si oke, oko ofurufu ni awon yio gbe si losi oke, bi o ba ku bi ogun maili (Miles) ki oko Ofurufu yi de inu Osupa, ero ti nwon gbe sinu re yio jade funrare, yio si ma lo taara si oju Osupa, ti o ba ti de ohun ti o se gbogbo nkan ti o ba lo tan, yio ranse si nwon ti o ran lati aiye, Ohun ti oju re ri ni ohun.

## Iya kan salaisi awon omo re meji ku tele.

Agbo irohin lati ilu Onitsha ni pa obinrin kan ti o nje Mgbafor Okafor ati awon omo re meji ti o nje Josephine ati Ngboukwo ti gbogbo w o n k u iku aburadi.

Nitori idi oro yi ni awon olopa se yan awon oghoju ninu ise Otelemuye lati wa se itose oro na, abule ti a gbo wipe nkan na ti sele ni eyiti nwon npe Ukpor

Ise awon olopa na ni la ti wa di gbogbo asiri ti o mbe ni idi oro na, ati bi nwon se pa obinrin na Mgbafor ati awon omo re mejeji.

Obinrin na ati omo re mejeji ba won lo si bi ase kan ti nwon n pe ni Mbali, ni be ni nwon gbe ti jeun, ti nwon si ku si ohun, ki nwon to lo sin oku gbogbo won.

Sugbon awon olopa fa oro na ta wipe, oro na ko ni ku sibe, nwon ni lati wadi re, nwon lo hu oku obinrin na ati omo re ni biti nwon gbe sin i si, nwon si gbe lo fun ayewo ni ile alaisan ni Onitsha. Awon olopa si mbe lenu oro na, nwon nse iwadi oro na lowo.


## Ha! eti re melo?



Eyi yi ni Ero Alata to dara ju gbogbo eyi ti won ti nlo tele ri lo, lehin ata lilo, o tun le lo Igbado ati Oka-Baba, ati Ewa-ere orisirisi.

**£45 ni a nta** Pelu Enjinni Petrol tabi ati pelu Eletiriki Muto.

WA NI SOBU

**Akoshile Brothers**

5, Balogun Street West,
P. O. Box 599
Phone No. 24395, Lagos.


Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16 Bamgbose street, Lagos Phone: 21985 Olotu: E. A. Adenji 51 Tejuosho Street Suru-Lere YABA
FUN OWO IROHIN IMOLE ODUN KAN
EKO Sile Merin ati Kobo Merin (4/4d)
Ilu miran N. Naijiria ati OKE-OKUN Sile Mefa ati Kobo Mefa (6s/6d)

## Kini a npe ni Islam.?

Lati Owo:— MAULVI N. SAIF Lagos.
OBERE LATI OJU EWE KETA

Iwe Mimo Kurani so fun wa wipe "nisisiyi Olorun ti se esin Islam ni pipe, awon ti o ba tele esin Islam ni a npe ni awon Musulumi. E mase pe won ni Imale mo, Oruko o dara fun ni "Islam" e mase pe ni Mohamediya mo.

Enikeni ti o ba ni oro lati bere nipa oro Islam, ki o kowe si:- Maulvi N Saifi, ni P. O. Box 418, Lagos.

NIGBATI OBA ILE JORDAN wa be Ilu Eko wo, awon ijo Musulumi nikan soso lo lo pade re. Oba Eko wa ninu won, ati awon Ijoye re meji. Lemomu Jamiyu Ilu Eko, ati Malvi Saifi. Awon Ijo Musulumi nwonyi fi ebun Iwe Olowo iyebiye ta Oba ile Jordan na lore, o si fi tayo tayo gba a. Nassar ile Egypt ti pari ibewo re tan nile Pakistan o ni ki B a b a Egbe ile Pakistan wa be ile Egypt wo. Ayub Khan ti ise Baba Egbe ile Pakistan si ti gba lati se be.

## "Nipa Ise Haji"

Lati Owo:- ALUFA HUSAEN MUHAMMAD.
OBERE LATI OJU EWE KETA

Muna ni ibi aye asetani ti ntan Isimaila lati ma gba ti baba re nigbati Olorun ni ki o dubu re. Won yio ma fi ojo meteta ni ju oko si awon aworan esu ti won ya si ibe ni amin ati ipinu ati ma tun se ise esu mo ni gbogbo igbesi aiye won.

Lehin eyi won yio dari si Moka pada lati se ipalemo tabi Tawaf ifaarati lati mura lilo si Modina.

## Ominira wa ti daju ninu osu kewa Odun yi

YORUBA NPA OWE Bayi wipe, bi a ba ti fa agbo fun Egungun, ise ni a nju okun re silo. A ti gba wipe awon Geesi yio fun ile Naijiria ni Ominira ninu osu October ti o mbowa yi, bawo lo tise tun di wipe e tun mbo wa joko ti wa lorun lehin ti e ti fun wa ni Ominira tan.

Ninu odun 1958 ti awon asiwaju wa lo silu Oyinbo a gbo wipe nwon ni k won towo bo iwe adehun kan wipe lehin Ominira Ijoba Ile Naijiria yio fi ile nla tamu-tamu kan fun awon Geesi nitosi Ibuso oko ofurufu lati fi se ibudogun fun awon Geesi.

Kini nwon tun nfe ibudogun ti wa lorun fun Ibudogun wa ni Eko, ati Ibadan, Kaduna, K a n o, E n u g u, Kalabar ati ni Kamerun.

Ogbeni Ian Macleod so fun Igbimo Commons wipe, nwon ti pari oro Ominira, fun ile Naijiria, on si ti se tan lati te oro na siwaju Igbimo Palamenti ninu osu June.

Gbogbo awon asiwaju Ijoba ile Naijiria ti nwon lo soro na pari lo njo ti nwon si nyo wipe n i n u awo Oniwura ni a gba Ominira wa si, a si g b o pe ayo ni a w o n iko wa mba bo wa sile.



ALHADJI TAFAWA BALEWA

## IWE EBE

A fi eyi jirebe lati bebe lodo awon meji ti oro inu iwe wa ti ojo kerindilogun osu b wi, ki Fa'mi ati Ereibeji fi ori ji wa oruko awon meji yi ko si ninu awon ti o pa egun ti o nje Mufu Gbangbose, a ise pi

Awon ti o pa ni, Shitta Lagunju, Taoridi Olasi okomi, Yesufu, Raimi, Ereibeji kosi ninu awon to pa egun na.

Olotu